## ṢÍṢE ÌGBÉLÉWỌ̀N FÚN KÚWÍKÍ DÁÀṢÌ

Ọ̀nà méjì ni à ń gbà láti ṣírò kúwíkí daàṣì: ìpín àìlera/àpẹẹrẹ (ìbéèrè mọ́kànlá, èyí tí a fún ní nọ́mbà kan sí márùn-ún) àti módùlù tí kò pọn dandan tí eré ìdárayá/orin tàbí iṣẹ́ (ìbéèrè mẹ́rin, èyí tí a fún ní nọ́mbà kan sí márùn-ún).

## IYE ÌPÍN ÀÌLERA/ÀPẸẸRẸ

Ó kéré tán, mẹ́wàá nínú mọ́kànlá ni olùdáhùn gbọ́dọ̀ dáhùn kí ó tó di pé a ṣe ìṣirò. Iye nomba tí a fún àwọn ìdáhùn ni a má a rò papọ̀, tí a ó ò sì gé, láti fi ní iye kan nínú márùn-ún. Iye yìí ni a óò sọ di iye kan nínú ọgọ́rùn-ún nípa yíyọ oókan kúrò nínú rẹ̀ àti písọ ọ́ di púpọ̀ pẹ̀lú márùn-ún-dín-lọ́gbọ̀n. Àyípadà yìí wà fún mímú kí ó rọrùn láti ṣe àfiwé rẹ̀ pẹ̀lú àwọn ìwọ̀n mìíran tí ó wà láàárín òdo sí ọgọ́rùn-ún. Ibi tí iye kan bá ti lọ soke ń tọ́ka sí àìlera tó pọ̀ púpọ̀.

Àìlera dáàṣì/àmi àpẹẹrẹ = $\left[\left(\frac{\text{àpapọ̀ iye ìdáhùn}}{n}\right)-1\right] \times 25$

n dúró fún iye gbogbo ìdáhùn tí olùdáhùn dahun

Àwọn módùlù tí ò pọn dandan (Eré ìdárayá/Orin tàbí iṣẹ́)

Módùlù tí ò pọn dandan méjì ló wà, èyí tí ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn sì ní ìbéèrè mẹ́rin. Àwọn módùlù tí ò pọn dandan yìí wà fún àwọn eléré ìdárayá, olórin tàbé òṣèré àti ọ̀wọ́ àwọn òṣìṣẹ́ tí iṣẹ́ gba agbára púpọ̀.

Àwọn wọ̀nyí lè máa ní ìṣòro nìkan níbi tí iṣẹ́ bá ti gba agbára jù, èyí to kọjá àfojúsùn Kúwíkí daaṣì onímọ́kànlá.

Ìlànà yìí kan náà tí a ṣàpèjúwe fún ti Iye Ìpín Àìlera/Àpẹẹrẹ ni a óò ṣàmúlò fún módùlù ìpín tí ò pọn dandan oníbèérè mẹ́rin. Gbogbo ìbéèrè ni ó níláti wà ní dídáhùn kí á tò lè ṣe ìṣirò rẹ̀. Fún módùlù kọ̀ọ̀kan, ro gbogbo iye tí a fún ìbéèrè kọ̀ọ̀kan pọ̀, kí o sì pin pẹ̀lú mẹ́rin (iye ìbéèrè); yọ

óókan kúrò nínú rẹ̀, kí o sì sọ ọ́ di púpọ̀ pẹ̀lú márùn-ún-din-lọ́gbọ̀n láti lè ní iye kan nínú ọgọ́rùn-ún.

## IYE ÀLÀFO

Tí ìdá mẹ́wàá nínú ọgọ́rùn-ún (ìyẹn ni pé, bí ó bá ju ẹyọ̀ kan lọ) bá wà ní àìdáhùn, o kò lè ṣe ìṣirò iye àìlera/àpẹẹrẹ ti kúwíkí daàṣì/quick dash. Nipa òfin

yìí kan náà, (ìyẹn ni pé kò gbọdọ̀ ju ìdá mẹ́wàá nínú ọgọ́rùn-ún tí ó lè wà ní

ìṣòfo), a kò lè gbà kí ìṣòfo wà nínú módùlù tí ò pọn dandan nitori módùlù kọ̀ọ̀kan ní ìbéèrè mẹ́rin péré.

Institute for Work & Health 481
University Ave., Suite 800
Toronto, ON Canada M5G 2E9
Phone: (416) 927-2027 ext. 2173
Fax: (416) 927-4167
E-mail: dash@iwh.on.ca
Web site: www.dash.iwh.on.ca

Institute for Work & Health | Research Excellence Advancing Employee Health

© INSTITUTE FOR WORK & HEALTH 2006. ALL RIGHTS RESERVED.